# BI ỌLỌRUN KO LANI, ỌBA KAN KO LE LANI

NIGBA Iwaṣẹ, awọn ọrẹ meji kau mbẹ, orukọ ẹnikini a ma a jẹ "Enia lole lami" ẹnikeji a ma a jẹ "Ọlọrun loto mi la" iwa awọn mejeji ba ara wọn dọgba. Eyiti awọn agbalagba maa npa lowe wipe "Iwa jọwa l'onjẹ ọrẹ jọrẹ" Toto o, ki owe na o jẹ ti ẹnyin agba o.

Awọn ọrẹ meji yi, nwọn ko nipiṣẹ meji ti nwọn nṣe to ju orin kikọ lọ, nigbti nwọn ri wipe, orin wọn ko tun ta mọ ninu ilu wọn, nwọn pinnu lati gbe iṣẹ orin na lọ si idalẹ, nipa bẹ, boya awọn le ti bẹ di Olowo.

## IRIN AJO BẸRẸ

Nigbati nwọn mura tan lati fi ilu wọn silẹ, "Enia lole lami" sọ fun "Ọlọrun loto mi la" wipe, ti a ba de ilu ti a nlọ, maṣe jẹki a kọ orin miran to ju "Enia lole la wa" lọ boya bi a ba nṣọ bẹ, orin awọn ara ilu na le wu lati le ma a fun wa lowo. Ọlọrun loto mi la" da a lohun wipe, orukọ tirẹ niyẹn, iwọ le ma a sọ bẹ nitemi, nko ni ba ọ sọ bẹ "Ọlọrun loto mi la" ni orukọ temi, ohun ti ngo si ma fi kọ orin temi niyẹn. Ọrọ yi ko dun mọ "Enia lo le la mi" ninu ṣugbọn, nwọn palẹ ẹru nwọn mọ. nwọn doriko idalẹ ti nwọn nlọ.

## ẸLẸRẸGBẸ

Nigbati nwọn de ilu ti nwọn nlọ, nwọn kotete ri ile desi, ṣugbọn nipa orin didun ti nwọn nkọ kiri ilu Ẹlẹrẹgbẹ kan bi ti wọn gba wọn sile, nigbati o di ọjọ keji ti wọn ti wọlu na, nwọn bere lọwọ ẹniti nwọn de sọdọ rẹ wipe, Tani a le korin wa yi fun ninu ilu yi, ti o le fun wa lowo to jọju? Ọkunrin ti nwọn de si ile rẹ sọ fun wọn wipe, kosi ẹniti ẹ le korin yin fun. ti o le fun nyin lowo pataki bikoṣẹ Ọba ilu na.

## NWỌN DE ILE ỌBA

Awọn akọrinta yi bere wipe, kini oriki Ọbana ti njẹ? ọkunrin yi sọ fun wọn wipe, Ọba ilu wa yi ko ni Oriki meji, to ju 'Fowosere Akanbi' lọ. Lẹsẹkẹsẹ, awọn Akọrin ta yi dide nwọn dorikọ ile Ọba na, bi wọn ti nlọ, "Enia lole la mi" tun sọ fun "Ọlọrun loto mi la" wipe, jọwọ, bi a ba nlọ yi o, bi a ba de ile Ọba ti a ba bẹrẹsi kọrin, Enia lole la wa ni ki o jẹki a ma fi kun orin wa o "Ọlọrun loto mi la" da a lohun wipe rara o, emi ko ni sọ bẹ ẹ, Ọlọrun loto mi la, ti iṣe orukọ temi yẹn gan on ni ngo ma fi kọrin temi, ti mo ba nfi kọrin bi o ba wu Ọba ti a nkọrin fun ki o fun mi lowo, bi ko ba si wu u ko ma fun mi. Nigbati Enia lole la mi gbọ bẹ, o dakẹ, nwọn nlọ, nigbati o kusi dẹdẹ ki nwọn de ẹnu ọna ile Ọba, Enia lole la mi lo kọkọ bẹrẹ si kọrin, o nkọrin rẹ na bayi wipe:- Kabiyesi, Ọba Alaṣẹ ekeji Oriṣa, Fowosere Akanbi loto mi gba nigba ipọnju, Arowo-ṣe-fuya lawujọ, Ọkunrin kọrọbọtọ bi ọka; Baba gbadegẹṣin.

Ọkunrin yi bẹrẹsi kọrin ki Ọba yi nikan ko jokan nigbati o kọrin tirẹ tan o dakẹ, "Ọlọrun loto mi la" bẹrẹ orin tirẹ ni kikọ bayi: Fowoṣere ko le lami,, Ọlọrun to fun ọ nipo a ṣe temi, Iranlọwọ Oluwa ni mo duro de.

## INU BI ỌBA

Ah! Nigbati Ọba gbọ orin ti "Ọlọrun loto mi la nkọ, O dide fun lori aga to fi joko ninu afin rẹ, ọ yọju sita, o pe Ọlọrun lo to mi la, o sọ fun un wipe da orin rẹ duro na, o sọ fun "Enia lole la mi" o ni ki o tun kọrin tirẹ ki on gbọ Enia lole la mi tun kọrin rẹ gẹgẹbi o ti nkọ ti o fi nwa oju rere Ọba, nigbati Ọba gbọ orin rẹ lẹkeji, o ni ki o tun dakẹ ki on tun gbọ orin ti "Ọlọrun loto mi la" lẹkan si, "Ọlọrun loto mi la" tun kọrin rẹ gẹgẹbi o ti nkọ. nigbati Ọba gbọ orin "Ọlọrun loto mi la" to tan kọ, o rẹrin iya-gi o fi itọ popa sinu, o tu itọ tuntun sode, o pinnu lọkan ara rẹ wipe, on yio sọ "Enia lole la mi" di Olowo o pinnu wipe, bi Ẹgbẹji Olori Oniṣẹgun nfọ ori fun "Ọlọrun loto mi la" on yio sọ di Alakisa ki o to kuro ninu ilu on yi.

Ero ọkan ọba yi si "Ọlọrun loto mi la" mu mi ranti orin kan ti awọn Alufa ma a nkọ wipe:- Baiye l'on o ṣẹgọ, o ko ni lẹgbagbe.



Ogbẹni ẸRUKOBODO

Ma bẹru eleyi on ni, ṣa bẹru Oluwa,
Kosi ohun t'o nṣe nibikan ki Oluwa ma mọ,
Ko ṣ'ẹhin Oluwa mi Oba a ṣe kan ma a ku.

Ki awọn Akọrin ta yi to kuro nile Ọba, Ọba fun wọn ni ṣile kọọkan, osọ fun wọn wipe, bi o ba di ọla ki nwọn tun wa, ati wipe, lati ọla lọ titi di ọjọ ti ẹ o ba kuro ninu ilu yi ni ki ẹ ma a wa kọrin yin fun mi.

## ỌBA RA AGBỌN

N'gbati awọn Akọrin ta yi lọ tan, Ọba pe iranṣẹ rẹ kan, o sọ fun wipe, ki o lọ ka Agbọn ati ekiri ẹja nla ran wa, nigbati Iranṣẹ na ra a de, Ọba da Agbọn na lu, o ko owo beba oni pọnun mẹwa sinu rẹ (£10) o di i pa, ti o fi jẹ wipe kosi ẹniti o le mọ pe nwọn ti da Agbọn na lu si.

Ki ilẹ ọjọ keji to mọ, Awọn Akọrin ta yi ti tun dele oba, ohun orin wọn lo ji awọn to sun ninu Afin "Enia lo le lami" nkọrin ki Ọba mẹsan mẹwa.

"Ọlọrun lo to mi la" ko korin ju ohun to ti nṣọ lọ. Nigbati o to nkan bi agogo mẹjọ owurọ, Ọba pe ọkan ninu awọn iranṣẹ rẹ o ko, agọn ati ẹja fun un. O ni ki o gbe Agbn ọti owo wa ninu rẹ fun "Enia lole lami" O ni ki o mu ekiri ẹran fun "Ọlọrun loto mi la" o tun ran Iranṣẹ rẹ yi si wọn pe; ki nwọn o ma a lọ, ti o ba di ọla ki nwọn o tun wa.

Bi Iranṣẹ Ọba ti jiṣẹ fun wọn tan, nwọn dakẹ, nwọn nlọ, nigbati nwọn nlọ, ti "Enialolelami" ri ọra to wa lara ẹja ti Ọba fun "Ọlọrun lotomila" o sọ fun Ọlọrun lo to mi la wipe, ọra ma pọ lara ẹja yi jẹki a ṣe pasiparọ, ki iwọ gba agbọn ki emi gba ẹja ọlọra rẹ.

"Ọloruntomila" wipe ko ba wiregbe kankan o gbe ẹja fun un, o gba Agbọn lọwọ rẹ, ki nwọn to dele "Enialotomila" fọ agbọn o ba owo (pọnun mẹwa) ninu rẹ, o ko pamọ, ko sọ nkankan fun ekeji rẹ, nigbati "Enialololami" jẹ iwọnba ti yio jẹ ninu ẹja tan, o lọ ta iyoku ni ṣile meji abọ, on na fi owo tirẹ pamọ ni alaisọ nkankan.

## ỌBA NFUN WỌN LOWO

Ni ojojumọ fun odindi oṣu mẹfa ni nwọn nlọ nkọfun Ọba, ti Ọba si nfun wọn ni nkan kan na, ati wipe lẹhin ti nwọn ba fun wọn tan ojojumọ na ni "Enialolelami" nfi Agbọn ti Ọba ba fi fun ṣe paṣiparọ gba ẹja lọwọ "Ọlọrun lotomila" "Ọlọrunlotomila" gba ra o nko owo to ba ba ninu rẹ pamọ, bẹni "Enialolelami" papa ntu ṣile meji-abọ ti o nta Ẹja tirẹ na jọ. awọn mejeji ko fi asiri owo ti ẹnikọkan wọn ri han ara wọn.

Wo Oju Ewe Karun

# IWE SI OLOTU

## Eleyi Nfẹ Amojuto

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati ke si Ijọba Ibilẹ ti ilu Ijẹbu-Imushin lati ṣe amojuto gbogbo ọna ti o wa ni agbegbe ilu na gẹgẹbi Iwasi. Igbagba ati Imuwen to jẹ pe ọpọlọpọ awọn ohun tita to nti awọn ilu wọnyi wa si ọja ti ilu Imushin ati pe ni asiko ojo yi awọn ọna ilu na ko dara fun awọn onimọto ṣe awa ara ilu na ko ki nfi owo ori wọn jafara, ọdọọdun ni a nsan owo ori.

Ọpọlọpọ iṣẹ ni awọn Ijọba Ibilẹ Ijẹbu Imushin fisilẹ ti nwọn ko ṣe, iru awọn nkan wọnyi ni omi-ẹrọ ti ko kari gbogbo ibi to ni lati de ni agbegbe ilu na tabi ti ko to ninu ilu miran gẹgẹbi Esure omi ẹrọ to yẹ ki o wa nibẹ ni lati to bi mẹwa. Ṣugbọn awọn Ijọba Ibilẹ na ko si fi ju mẹta si ilu.

Inu mi yio dun bi awọn Ijọba Ibilẹ na ba mura ṣidigidi fun awọn nkan wọnyi.

Mo dupe pupọ o, Olotu. ẹo ma ni Ilọsiwaju ninu iṣẹ nyin o, amin.

Emi ni
OMOLUWASI,
Eko.

## Kini Ki Baba Ṣe

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi ni aye die ninu iwe nyin to nkọwa ni ọgbọn ati oye lati bere ọrọ ti o ru ni loju yi lọdọ awọn ti ori wọn pe ati awọn omiran to le mọ oyun inu igbin.

Baba kan wa to bi ọmọ mẹfa, baba yi jẹ talaka, wara ti i y a baba yi ku ni oba ko awọn ọmọ mẹfẹfa kuro ni ilu, o si gba idalẹ lọ.

Nwọn de idalẹ, baba yi ko ri iṣẹ to rara ojẹ onile rẹ ni owo ọdun mẹta ni onile ba sọ fun pe on ko ni ba ja rara' ki o k o gbogbo nkan rẹ ki o si jade ninu ile fun on. Nitoripe on fẹ lo ile.

Baba yi ati awọn ọ m ọ rẹ ndamọran ekini n i k i awọn lọ gba ile miran, ekeji ni ki awọn pada s i ilu awọn, ẹkẹta ni awọn ko gbọdọ jade ninu ile na rara, ẹkẹrin ni ki awọn lọ kọ ti awọn, ẹkarun n i ki iwọn gbe ibiti a wọn ba ri ati kẹfa ni ki awọn kuku si oogun pa orilẹ na,

Ejọwọ tita ni ki b a b a yi gbagbọ ninu awọn ọmọ mẹfẹfa yi

Emi ni
CELINAH ORỌLAJA
Ijẹba-Mushin

## Ọkunrin kan ku ni ọjọ Kẹta Ti ọ Gbe 'Yawo

SHOGUNLẸ:- Lẹhin inawo rẹpẹtẹ pẹlu ayọ igbeyawo ni Ogbẹni Ọlanipẹkun Alao ẹni ọdun mẹrindinlọgbọn ti o ṣẹṣẹ ṣe igbeyawo larin ọjọ kẹta na ni a si gbo pe o jalaisi, ninu ile rẹ n opopo Ajilia, Shogunlẹ.

Ọpọlọpọ awọn enia to wa ba Ogbẹni Alao ṣe inawo ti igbeyawo na lo si hu si ẹkun nigati nwọn gbọ iku rẹ.

Awọn aya ile ọkọ iyawo na sọ iru nkan to pa Ọkunrin na pe ko ye awọn.

Nwọn si tun fi ye Onirohin wa pe larin wakati kan si igba ti wọn fi gbọ pe O jalaisi pe ko si nkan kan to nṣee atipe ara rẹ si le daada.

X Onirohin wa tun fi ye wa lati Makurdi pe Ọkunrin kan ti o jẹ Oludari ile itaja itura Ogbẹni Johnson Ugwa si jalaisi ninu iyara rẹ. Nwọn fi ye Onirohin wa pe Ọkunrin na lo si fi ibinu pa ara rẹ.

## Igi Wolu Ọkunrin Kan

KALABAR:- G b o g bo oṣiṣẹ ti ile iṣẹ Ọbọ Ọba Oban ni Kalaba si da iṣẹ duro nigbati nwọn gbọ pe ọkan ninu wọn, igi nla kan si ti wo pa ọkunrin na ti orukọ rẹ njẹ Okon Akpan ẹni ọdun mẹrindinlọgbọn.

Ogbẹni Okon Akpan si wa lenu iṣẹ nigbati o nge igi na ti igi na si wo pa a lojiji.

Ọkunrin na si kegbe nigbati igi na wo lu ṣugbọn ki awọn oṣiṣẹ ẹlẹgbẹ rẹ to de ibẹ Akpan si ti ku. Awọn ẹlẹgbẹ rẹ si ti gbe oku ọkunrin na lọ si ile iwosan lakulaku ni Kalaba.


# Gbanjo o !

Eyi ni lati kede fun gbogbo awn ONIBARA wakọ jake jado agbaiye pe ao bẹrẹsi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbano yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Colonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tete bẹrẹ GBANJO na.
TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 28th MAR.–30th APR

| | | | |
|---|---|---|---|
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/— | di | 22/6d |
| Iwe Ilana Ifa, Iyanrin tite Etutu ṣiṣe | 21/- | di | 18/- |
| Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba Psalm Isẹgun Aje | 4/6d | di | 3/- |
| Iwe Ala Nla | 7/6d | di | 5/6d |
| Iwe Ala ati Iwadi Nkan | 2/6- | di | 2/- |
| Turari Isẹgun Ajẹ | 10/6 | di | 8/- |
| Certificate of Appreticeship | 7/6d | di | 5/- |
| Tailor's Measurement Book | 7/6d | di | 5/6d |
| Iwe Itan Ala | 2/6d | di | 1/- |
| Iwe Itumọ Ami Ara | 4/6d | di | 3/- |

AKIYESI:— Ẹnikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

Shoyinka
42/99 Shittu Street
Ibadan



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọn mọnọ

**RICHALET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe n TỌNIKI Ẹẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyọn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba awọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun. Jẹdiẹdi Akọ ba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalap Egbogi-n Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didu tabi baradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogi kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si n ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

## Direba Ati Enia Meji Ko Ijamba Moto

Laipe yi ni awon enia meji ati Direba inu moto ula kan si fi ara pa ninu ijamba moto to sele ni ona Ibadan si Shagamu.

Awon enia meji ti nwon si fi ara gbogbe pupo na ni Saka Alabi ti abule Akin ni eba Egba Obafemi ati Nuratu Tijani ti ngbe ni Abul Degesin ni eba Egba Obafemi lagbegbeAbeokuta

Nwon si gbe awon enia na ati Direba na lo si ile iwosan tiAdeoyonilbadan.

Awon olopa fi ye onirohin wa pe Direba moto na ko iti ni oruko gege bi ati nkoiwe yi ati pe won ko mo awon enia re.

Onirohin wa tun fi ye wa pe ijamba moto kan na tun sele ni Ibadan si omode binrin kan ti oruko re nje Mogbonjubola eni odun mejila ti o ngbe ni ile eko giga Unifasiti ti Ibadan.

Awon olopa si tun fi ye Onirohin wa pe ijamba na sele nigbati omo na fe fo ona si odi keji. Were ti moto gbe omo na sanle ni nwon ti gbe lo si ile iwosan ti Unifasiti ni Ibadan.

### Odaran Kan Sapamo sinu Apo Iwe

Ariwo ta nigbati won ri Odaran ole Okunrin kan ninu apo ti awon akowe rin fi ko iwe ni ile ise ifi iwe ranse ni Owerri ti Okunrin na si fi ara re pamo lati fo ile ifi iwe ranse na.

Okunrin jaguda yi si lo si ile ise ifi iwe ranse lati lo wo ore re ti nsise ninu ile ifi iwe ranse na (Post Office) Okunrin na si ba ore re soro die titi ofi so fun un pe oo mbo ti o si fi ara re pamo sinu okan inu awon apo ikowe na.

Nigbati ore re to nsise ninu ile ise na fe mura lati ma lo si ile, o si pe ore re to ti ba sire lekan su—gbon nigbati ko ri lo ba mura lati ma fi awon iwe sinu awon apo na, ni o si ri ore na ninu apo nibiti o fi ara pamo si, ni ore olosa na ba kegbe titi awon olopa ati awon enia to wa nibe fi mu Okunrin Odaran na lo si ogba awon olopa, Awon olopa si ti nse iwadi oro na lenu Okunrin olosa na.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 21-Feb 19) – Ayo ati igba olo yinmomo mbe niwaju fun o, bi o tile je wipe kole se ki o ma si ayipada.

PISEES (Feb-20-Mar 20) – Ohun ti o dara fun o lati ma lepa ni Alafia, mase ma garun wo nkan oni nkan kakiri.

ARIES (Mar 21-April 20) - Obinrin arewa kan yio se oni rere, sugbon Obinrin na je eniti o mo ti ara re nikan.

TAURUS (April 2 -May 21) – Nkan iyanu kan ti o ko 'rotele yio sele, yio si di ya agbalagba meji.

GEMINI (May 22-Jun 21) – Ise kise to wu ki o le ma se ni ode gbangba, ni eyiti o dara fun o lati se.

CANCER (Jan 22-July 23) – Ojo ija ni ojo oni, okan ninu awon enia re ni yio ko o sita.

LEO (July 24-Aug 23) – B o ba fe lo si ode, oni ni ojo to dara lati se be.

VIRGO (Au 24-Sept 23) – Avipade mbe lojo ti oni, sugbon nibiti nwon gbe nse ere ayo ati inawo, ibe ni ki o lo.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Awon ore yio se ore fun o loni, iwo yio si gba alejo kan lale oni, ti yio si fi oro iruju kan si waju re.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Gbamoran agba gbo ohun ti o ndamu re, yio si kuro.

SAGITTARIUS' (Nov 24-Dec 22) Ohun rere kan yio sele si o ni akoko ti a njeun ale.

CAPRCORN Iwa ife yio fara han larin awon ebi re, ohun kekere kan ni yio si da ife na sile.


## Iboosi Iko Ti Oju Ile Ti Pe Lara

Pupo ninu awon egbogi robirobi ti won npolowo ti won si nta kakiri igboro ilu Eko ati ni igbereko ko le se iwosan won laili afi ki o ri ojulowo hauuhaun atamatase egbogi ti o lagbara gidigidi ti o le se iwosan re titi de inu ifun ati igba-aya, ti yio mu o ma tu "Iko" mo bi kelebe jade ti o ba nhu o titi yio fi tan ni inu re patapata. Awon iko miran wa ti o dabi enipe won a ma ja ogun tabi orisirisi egbogi tabi ti o ba je pe beni, agba O ni imoran wipe ki o ma lo egbogi awon ara ilu Abyssinia ti won npe ni "Etibard" pelu egbogi ti o ba nmu.

PORAL TABLETS
THIOLYPTINE SYRUP
THYMO-EPHDRIN LINITUSS
ETIBARD ABYSSINIA POWDER

Fun iwosan iko Asima, iko fere iko otutu igba-aiya iko gbedu, iko-onafun, iko-gbigbe tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ona-ofun tabi pelu kelebe tabi ti o ma nje ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara losana ati loru-gbiyanu' lati dan okan ninu awon egbogi alagbara gidigidi wonyi wo fun ara re iwo yio si ri iyato gburugburu larin won si awon olomi sorokiti ti won nta kakiri.

O daju nibe iwo yio bere si ri alafia, iwo yio ma eun daradara wasi ma sun fonfon pelu Alafia de si o ni yen

Bere ni Sobu awon:—

Bere egbogi ajebina Richelei y ni sobu awon

Waterloo Medicine Store
8, Plamchurch Street,Lagos
Phone:–22878 Nigeria, (Oja ita Faji)



# Kere o !

Fun anifani gbogbo enyin onisowo, Iwe Irohin Imole yio se ipolowo awon oja nyin fun nyin ti ose kan gbako ki odun Ileya o to de ati lehin odun ki awon onibara nyin le ba nyin ra oja odun Ileya ti mbo yi.

Awon Asoju wa yio ma a lo kakiri lati be re fun awon ti o ba fe lati polowo oja won ninu Iwe Irohin wa.

Owo pooku ni a ngba, dan wa wo lekan ki o sribi ajo re yio ti to, Ijafara lewu o.



## Iwo Ha Nlo Si Mekka Ni Odun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JE RI O, OLUWA MO JE IPE RE
enikeni ti o ba fe lo si "MEKKA" Ilu Mimo ni odun yi gbodo ni iwe
"AFINIMONA NPA ISIN HAJI"
LOWO KI OLUWARE MA BA SINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LO ALOBO MEKKA NA DADA

t'Oluwa jowo se Isin Haji wa ni eyiti o tona. Si jowo fun wa ni rere ti aiye ati t'orun Oluwa wa, ki o siso wa ni bi iya nitori IWO NI OBA alagbara Olubori gbogbo eda patapata" Amin

"WAS SALAM"

AKIYESI Gbogbo Musulumi Ododo oye ki o ni na lowo nitori igbati yio ba fe lo si MEKKA
Iye Owo 5/6, £3 fun dosini
MANAGER
N2/99 SITTU STREET
Ibadan

# Bi Ọlọrun Ko Lani

## Lati Oju Ewe Keji

### ỌBA PE AWỌN MEJEJI

Nigbati Ọba ti ri i wipe owo ti on ti fun 'Enialolelami", o ti to sọ ọ di olowo, ni ọjọ kan, o pe awọn mejeji, o sọ fun wọn wipe Ẹ da orin ti e nwa kọ fun mi duro loni. bi o ba di ọjọ mẹsan oni, mo fẹ ki ẹnyin mejeji ṣe ọṣọ gẹgẹbi ẹni kọọkan nyin ba ti ṣe ni owo lọwọ to, ki ẹ wa ba mi ninu Afin mi.

Ọba tun lu a g o g o pe awọn ara ilu rẹ wipe, ni ọjọ mẹsan oni on nfẹ ki t'ọmọde t'agba ko wa wo iran kan ninu afin on. Ki ọjọ yi to pẹ pe, Ọlọrunlotomila lọ ra agbada olowo nla. o ra ṣokoto ati ẹwu Gbariyẹ to ba agbada mu o ra fila olowo nla ti oko rẹ kun gbẹẹgbẹẹ, o ra Ẹṣin, o tun gba Apoko Ẹsin ti yio ma tọju Ẹsin na. Ọrẹ mi to sọ wipe enia lo to on la, o lọ fi iwọnba owo to ri tujọ ra igan itẹkọ kan, o da ni ẹwu Dansiki kan, Ṣokoto Agbada kan ati Fila Abeti-aja owo tan.

### NWỌN TUN KỌRIN

Nigbati ọjọ pe, Ọlọrunlotomila gun Ẹṣin, o yọ si arin apejọ na gẹgẹbi Ọba, nigbati o ku si dẹdẹ ko de Afin, ti awọn onifere Ọba ri i ero ọkan wọn ni pe, Ọba kan lo mbọ, nwọn bẹrẹsi fun fere wọn fun un. Ọrẹ mi to ni Enia lo le la on nf'ẹsẹ rin bọ lẹhin rẹ, o dabi ẹru-ọba lẹhin rẹ.

Nigbati o ku si dẹdẹ ki Ọlọrun lo le la mi de ọdọ Ọba, o bẹrẹsi kọrin rẹ gẹgẹ bi o ti ṣe ma a nkọ bayi wipe:- "Fowo sere ko le la mi, Ọba to fun ọ ni iyi lo le to emi na fun mi," iranlọwọ Oluwa lo ju. "Enialolelami" na nkọrin tirẹ gẹgẹbi o ti nkọ bayi wipe:- Kabiyesi o! Ọba A l a ṣ ẹ ekeji Orişa, F o w o ş e r e Akanbi loto mi la nigba ipọnju, arowoşefuja lawujọ kọrọbotọ b'ọka Baba-gbadegẹşin.

Awọn mejeji bẹrẹsi kọrin titi wọn fi wọnu Afin Ọba, nigbati Ọba ri wọn, o jẹ ohun iyalẹun funfun nitoripe ohun t'o ro lọkan koto pe enia ilu rẹ jọ kọ lo tun ri, bi ọrọ yi ti ya Ọba lẹnu to bẹ to fi sọ fun awọn to pe jọ wipe, ko si ohun meji t'o mu mi pe nyin, bikose orin ti awọn arakunrin yi w a nkọ f u n mi. Orin na ni ẹnyin papa gbọ yi, nitoripe, lati ọjọ ti nwọn ti nwa kọrin wọn yi fun mi ni mo ti pinnu lati sọ "Enialolelami di Olowo ati wipe mo se gbogbo agbara mi fun to, şugbọn, o wa jẹ ohun to ya mi lẹnu lati ri "Enialolelami" bi Ẹru Ọba loni.

Bi ọrọ yi ti ka Ọba lara to, o pe "Enialolelami" o bere lọwọ rẹ wipe "elo ni o ni ni'pamọ" "Enialolelami" da Ọba lohun wipe, "iwọnba owo ti mo ni lọwọ na ni mo fi ra aşọ ara mi yi" Ọba tun bere lọwọ "Ọlọrunlotomila wipe, ngbọ elo ni iwọ ni ni ipamọ? Ọlọruntomila daa lohun wipe lẹhin ti mo ti ra Ẹşin ati gbogbo aşọ ti mo wọ yi tan, owo mi to mbẹ nipamọ ti ju ọgọrun ọkẹ lọ. Nigbati Ọba gbọ bẹ, o bere lọwọ Enialolelami wipe, tani ẹniti o ngba Agbọn ti mo nfi ran Iranşẹ mi ninu nyin? "Enialolelami" da a lohun wipe, Kabiyesi emi ni şugbọn, bi mo ba ti gba a tan, bi a ba jọ nlọ sile ni mo ma nfi agbọn na şe pasiparọ gba ẹja lọwọ Ọlọruntomila.

KO TI PARI


# Kere o !

Fun anifan gbogbo ẹnyintonişowo, Iwe Irohin Imọlẹ yio şe ipolowo awọn ọja nyin fun nyin ti ọsẹ kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lẹhin odun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Aşoju wa yio ma a lọ kakiri lati bere fun awọn ti o ba fẹ lati polowo ọja wọn ninu Iwe Irohin wa.

Owo pọọku ni a ngba, dan wa wo lẹkan ki o si ri bi ajo rẹ yio ti ta to, Ijafara lewu o.



BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Işẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IŞẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanşoşo ki o si ri iyatọ*


## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oşu yi (26/4/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba *16*, Bamgbose Street Eko.

A o si yan awọn Alaşẹ ẹgbẹ titun, eyi ti gbogbo ipade ti fi ohun sọkan lari yan ninu ipade ti a şe gbehin yi. Nitorina maşe alai ko wa, boya oye na le kan ọ.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Adele Akọwe


# Congreve.s Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu ririn nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni in nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio şe iwosan rẹ bi danga ni bi o ba ti la diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirişi omira pẹlu wọn mbẹ ni şọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone: 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 585 TUESDAY, APRIL 21, 1964 (2D)


## Ọkunrin Kan Fẹ Pokun So!

EBUTE—MẸTTA:— Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati o wa ninu ile kan ni 21B Aiyetoro Street, Ebute-Mẹtta nigbati nwọn ri ọkunrin kan, Rufus Lawson, ẹni ọdun mejelelogun ti o ki okun bọ ọrun rẹ ti o fẹ ṣo si oke aja ile rẹ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi.

Iyaafin Abẹkẹ Shekoni, ti ọrọ na ṣe oju rẹ ṣe alaye fun oniwe Irohin wa Ejongboro pe, bi on ti mbọ lati ode, ni on ri ọkunrin na ti o ti so okun kan mọ oke aja ninu ile, ti oṣi pojobo okun na ni isalẹ, bi o ti wo yika ile, ti ko ri ẹnikan, ko mọ pe on Abẹkẹ nwo on ni ọkankan, o gbe aga kan, o fi ti ẹsẹ, o si fẹ ki okun na bọ ọrun ki o ma a wa rọ loke bi ẹṣo pandọrọ ni on ba kigbe lohun rara ti gbogbo awọn enia be sare de.

Iyaafin Abẹkẹ ni, lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn aladugbo sare de, ti awọn si wa ba on gba ọkunrin na silẹ. Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn mu ọkunrin na lọ si Tesan awọn Ọlọpa ti o wa ni opopo Denton ni Ebute-Mẹtta lati mọ ohun ti o ndun ọkunrin na ni ọkan ti o fi fẹ pokunso.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa pe, awọn ti ṣe itọju ọkunrin na lati wadi awọn ọrọ diẹ lẹnu rẹ.

# ỌKUNRIN KAN LU ỌMỌ ẸGBỌN RẸ PA SINU OKO

AKURẸ:- Ọgbẹni Fabayi Williams, adajọ agba Ile ẹjọ ganran, ṣe idajọ pe ki nwọn lọ yẹ igi fun ọdaran kan, Ukperetire, ẹni ọdun mẹdọgbọn ti o nṣe iṣẹ apẹja nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun un pe, o pa awọn ọmọ ẹgbọn rẹ meji, James Wilson, ẹni ọdun mẹtala ati Jimmy Wilson ẹni ọdun mẹsan sinu oko rẹ nitoripe ẹgbọn rẹ kọ lati san owo ori iyawo ti o nfẹ si ọna ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun osu yi.

Bi adajọ ti nka idajọ rẹ awọn ero si nsọkun, nigbati adajọ sọ wipe on ti ri daju wipe lotitọ ni Ọdaran na pa awọn ọmọ mejeji yi larin oko rẹ ninu oṣu kẹjọ ọdun ti o kọja yi. O tun fi han wipe idi pataki ti Ọdaran na fi pa awọn ọmọde na nipe, o ti han pe ọdaran na sọ pe awọn obi ọmọ na ko fun on ni owo lati fi fẹ Iyawo.

Ibinu yi lo fa ti o fi lọ pa awọn ọmọ na sarin oko rẹ. Adajọ sọ pe daju daju, ọrọ awọn ọlọpa ti fi han pe enia buburu ni ọdaran yi. Nitoripe ọrọ owo ifẹ iyawo rẹ lo jẹ ki o lọ pa awọn ọmọde meji yi ti ki iṣe pe awọn ọmọ na lo ṣẹ ẹ.

Ninu ọrọ ọdaran yi, o sọ wipe ohun ti o fa ti on fi pa awọn ọmọde mejeji ni pe awọn obi wọn ti gbero lati lọ fi on ṣe ogun owo. Ati wipe, nwọn tiṣe ile ri pe awọn yio fi ẹjẹ on bọ oriṣa ilu wọn ti Isobo ti nwọn npe ni "Usighu"

Oni ọwọ ti on lo tete ya ti on fi pa awọn ọmọ wọn dipo on ti nwọn fẹ pa bọ oriṣa wọn.

Ṣugbọn adajọ sọ wipe irọ patapata ni ọdaran yi pa, ninu ọrọ rẹ.

Osi kọ lati gba ọrọ rẹ, ni o ba da ẹjọ Iku fun un gẹgẹbi ati ṣe wi siwaju.


## Kere o!

Fun anifin gbogbo enyin'onişowo, Iwe Irohin Imọlẹ yio ṣe ipolowo awọn ọja nyin fun nyin ti ọsẹ kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lẹhin ọdun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Aṣoju wa yio ma a lọ kakiri lati be re fun awọn ti o ba fẹ lati polowo ọja wọn ninu Iwe Irohin wa.

Owo pọọku ni a ngba, dan wa wo lẹkan ki o si ri bi oja rẹ yio ti ta to, Ijafara lewu o.


## Ko Si Ẹniti O fẹ Gbe Ogun ti Apapọ Ijọba

Lati Oju Ewe Kini

"Ewo ni ki a gbagbọ ninu mejeji?" o ni ọmọ lọ mu on lọ, o tun ni Ayọ Adesanya lo fi mọto gbe on lọ.

Ọgbẹni Olu. Ayọọla wa rọ gbogbo enia pe, ko si ẹlẹri pe, ọgbẹni Adesanya ba awọn enia ṣe ipade bẹni ko si ẹlẹri pe o ko iṣẹ ogun.

Lẹhin eyi ni ọgbẹni Olu. Ayọọla wa pari ọrọ rẹ pe adajọ ṣi ara re lọna o si kọja iwọntun wọnsi, lati gba ẹri Oleari ati Ọbọh gbọ ki o si kọ ẹri awọn iyawo Akinsanya.

Nigbati o sọrọ yi tan ni agogo mọkanla lu, o si pari ọrọ rẹ fun ile ẹjọ, lẹhin na ni Ọgbẹni Ọdẹsanya dide, pe enia mẹfa ninu awọn enia ti Ijọba mba ṣe ẹjọ ni on yio gbẹnuṣe fun.

Ṣugbọn o rọ Ile ẹjọ pe, ki nwọn gba on laye lati bẹrẹ ọrọ on nigbati Ile ẹjọ ba ṣiwọ fun isimi ti nwọn si pada de adajọ gba bẹ fun un, Ile ẹjọ si dide fun isimi ọgbọn iṣẹju.

Nigbati ile ẹjọ na bẹrẹ, ijoko wọn, Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya ṣe alaye pe, enia mẹfa ni on yio gbẹnuṣe fun awọn enia mẹfa na ni Omiṣade, Shashọrẹ, Akinsanya, Umoren, Nwaobiala ati Otubanjọ

Ọgbẹni Ọdẹsanyan ṣe alaye pe, ni tootọ ni, Ọgbẹni Ọtubanjọ lọ si Ghana ṣugbọn ko kọ iṣẹ Ogun ti o fi páda wale, adajọ ni o sọ ninu idajọ rẹ pe, ko kọ iṣẹ Ogun, ṣugbọn on ju sẹ-on nitoripe, o lọ si Ghana.

O wa rọ adajọ pe, ki nwọn o maṣe kọ ibi ara si ẹjọ ti adajọ na da, ki nwọn si gbe igi le idajọ akọkọ ki nwọn si da Otubanjọ silẹ nitoripe, ko jẹbi ẹsan, na.

Ọgbẹni Ọdẹsanya tun pe akiyesi ẹjọ ti Ibrahim Immam ro ni ile ẹjọ, pe Dokita Ọladipọ Maja wa sọ fun on (Imam) pe, Oloye Awolọwọ le on (Maja) lọdọ rẹ pe ki on ma de ọdọ on mọ nipa ọrọ nkan ogun, nigbati Awolọwọ ko gba si on lẹnu lo jẹ ki on wa fi ọrọ na han on ni Ipinlẹ Ariwa.

Ọgbẹni Ọdẹsanya ni ko si ẹniti o gbọ eruku Otu—banjọ ninu gbogbo ẹjọ ti nwọn ro silẹ, o wa rọ ile ẹjọ ki nwọn da Ọtubanjọ silẹ.

Ọgbẹni Ọdẹsanya ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe Ọgbẹni Nwaobiala ko gba owo lọwọ ẹnikan, ko si ba ẹnikan sọrọ Ogun tabi lati doju ija kọ Ijọba.

Nibiyi ni Ọgbẹni Ọdẹsanya ba ọrọ rẹ de ti agogo meji ku iṣẹju mẹdogun fi lu, ile ẹjọ na si pari ijoko wọn ti oni, ṣugbọn nwọn o tun ma a ba ẹjọ na lọ ni owurọ yi.

O darọ o.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Famgbọye Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 21/464